# IWE SI OLOTU IROHIN YORUBA

IDAHUN SI IBERE ǪLATUBǪSUN

Inu mi yio dun pupǫ bi ę ba le gba mi laye dię lati fi esi si ibere Ǫgbęni Samson Ǫlatubǫsun Ajiwoja Ǫlǫrun, ynji Gold Coast, eyi to jade ni 19/1/53 nipa ibere rę nnu Bibeli Mimǫ.

1 Pe kini oruko iya Mosasi B ba rę oruko iya rę ni Jokebedi si Baba rę si ni Amram a o ri eyi ninu ǫrǫ Ǫlǫrun Ekisodu ori 6 : 20.

2 Pe tani kętękętę ba sǫrǫ, Balaam Ǫmǫ Beori Alufa Ǫlǫrun kan ni nigbana a o ri eyi na ninu Numeri 22 : 27-31.

3 Pe Woli wo lofi ibantę ati gele rę wo enia san, Apostell Pauli ni, a o ri ni işe awǫn Apostell ori 19: 11-12.

4 Nipa oruko Baba Jobu emi ko iti kan ibę ninu Bibeli torişe ni ibere iwe Woli na a ri ka sibę pe ǫkunrin kan wa ara Usi, şugbǫ yio dun mǫ mi bi arakunrin wa na ba le toka mi si ęsę ǫrǫ na ninu Bibeli M'mǫ ngo si dupę—o.

Abǫ mi re o. Ebi alę ko si pa nyin o.

Emi ni ǫmǫ rę nisotę
David Adę Adedi-an
Baptist Church
KEFFI

IDAHUN SI IBERE ǪLATUBǪSUN

Inu mi yio dun ti ę ba le ba mi tete tę idahun, wǫnyi jade nipa ibere Ǫgbęni Samson Ǫlatubǫsun Ajiwoju Ǫlǫrun eyi-ti o jade ninu Iwe ti 19/1/53.

Idahun kini:-Amram ni baba Mose. Eks 6 : 20.

Idahun keji:-Belaam ni kętękętę ba sǫrǫ, Numeri 22 : 24.

Idahun kęta:-Esau ni Baba nla Jobu.

Idahun kęrin:-Apostell Paulu ni ęniti a nfi bantę ara rę şe işe iwosan. Işe-19 : 11-12.

Mo dupę o.

Emi ni
Prophet Peter A Oyinloye
Omu-Aran
VIA ILORIN

## Akiyesi

A fę ki awǫn ǫnkawe wa mǫ pe owe ni apo wa dodo, ęniti ko ba san owo iwe, ki o ma şe a lęsa bi a ba da a duro lojiji, a o si gba owo wa lǫwǫ rę

OLOTU
IROHIN YORUBA


"Fun Arun Wosewose, Lakuregbe Ati Orişirişi Iwo a

Elasto
THE BIOCHEMIC TABLET

È ti şe ti o fi dabi ęnipe arun miran wa ti ki i gb'oogun? ohun ti o nfa a ti a ko ti l'ero pe on ni ni a kǫ gbangba si isalę yi AIŞAN—YIKA IJẸ (BAD CIRCULATION) Egbogi titun ti o ntęjęsę ti oluwarę ko le fi ri irora kankan nivi "Elasto". Ti ęnia ba lo egbogi yi fi o ba ti ni arun lakuregbe, ęsę-wuwu, wosęwosę ati orişirişi arun ti aişan-yika-ęję ti mu wa gbogbo rę ni egbogi yi yio gbǫn danu bi idan, gbogbo agbara ati ilera oluwarę á wa di ǫtun. Tete lǫ ra egbogi Elasto ni Şǫbu egbogi ti o ba ri i, wa si fi ęnu ara rę jęwǫ pe ogun atata ni egbogi kekere na.


DORCAS ĘFUNDUN ANIKE ǪRUN'RE

ÁBULE TINDI-ABĘOKUTA—Obinrin rere ni Ada ǫkǫ rę" Ni ǫjǫ kini oşu keji ǫdun yi ni awǫn Şǫǫşi Tindi şe Isin iranti fun Ologbe Dorcas Ęfundun Anike Aya Ǫgbęni S. A. Sowunmi. Enia dabi omi, tian-tode Şǫǫşi lo kan o dabi ęnipe awǫn ǫdǫ awǫ Şǫǫşi rę ni.

Ologbe na fi aiye silę ni ǫjǫ kękanlelogbǫn oşu kini ǫdun ti o kǫja yi, o si fi awǫn ǫmǫ mętta wǫnyi silę Ǫgbęni Josaiah Sowunmi, Solomon Sowunmi, ati omidan Janet Sowunmi, ki Ǫlǫrun şe awǫn ǫmǫ na ni ęlęmi gigun.

Ęniti o şe Isin Iranti na ni Alamojuto Ijǫ Ǫgbęni Olaniade o si sǫ ǫrǫ iwuri pupǫ nipa Ologbe na bi o si ję ǫmǫ rere lati kekere rę wa ati bi o si ję olurantǫwǫ pataki fun baba rę ni Ile Olosun ni Ikopa.

O si tun şe irantiwǫ fun ǫkǫ rę lorisirisi ǫna ayiti o ji wipe ǫkǫ na ko le fi gbagbe rę lailai abasujǫ iku rę ni ki ǫkǫ rę fi şe aisan pupǫ nigbati obinrin na ku, bęni awǫn Ijǫ Şǫǫşi Tindi mǫ obirin na ni "Dorcas" totǫ larin Ijǫ.

Ki Oluwa tu ęgbǫn rę Raimi Ladipǫ, awǫn ǫmǫ, awǫn ębi, ǫrę ati Ijǫ Şǫǫşi Tindi ninu ki Oluwa si pese Olutunu pataki gigę bi Iyawo miran fun ǫkǫ na, Dorcas Ęfundun Anikę, alę mǫ ni igbagbe ǫrun rere o.


O Nwo Egbo San O Si Nmu Ara Gbe



Lo 'Mentholatum' fun egbo ati ekuru tabi kurunu. Lo o ni ojojumǫ. Ko nira rara lati lo. Iwǫ şa fi pa ibiti ti o ndun ę 'Mentholatum' nję ki awǫ ara dan borǫ-borǫ. O dara fun gbo gbo ohun ti o le yǫ awǫ ara lęnu. Nitoripe yio mu u kuro, yio si ję ki awǫ ara dan. Tete lǫ ra idę tabi agolo "Mentholatum" kan.

Sa Ma a Fi Pa ara



BERE FUN
MEN-THO-LAY-TUM



Ti nn agolo ati idę

Eyiti o ni pe Awǫn "The Mentholatum, Co. Ltd" (Est 1889) Slough, England nikan ni o nşe e.

MENTHOLATUM




ABIYAMǪ ETI RE MELO?

Abiku ǫmǫ nda ę l'amu bi !
Awǫn arun wǫnyi ba ayǫ ǫmǫ rę lęnu bi

AIPERI
ǪRĘRĘ
INU-IWǪ
OŞI
IGBONA
IKǪ
IGBĘ-ǪRIN
OTUTU
IBA
JĘDIJĘDI

ati orişirişi awǫn arun miran ti ima yǫ ǫmǫde l'ęnu ni igba EHIN HIHU. Lǫ ra "IYARO" awo Igba arun ǫmǫde ni fun gbogbo awǫn arun ti ima yǫ ǫmǫde l'ęnu

"YARO" ho pe mejì ni gbogbo Ilu Nigeria.

Ki iwǫ ki o ri i pe oruko "YARO" ni o wa lara Igo na ki awǫn ma ba ta adamǫdi egbogi miran fun ǫ.

